# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 868 LAGOS SATURDAY MAY 11—MAY 17 KOBO MEJI (2D) 1963

### Awon Osise Da Ise Sile:

## Oyinbo Onise Paapa F'aake Kori, O Ni Ko Si Ise Mo

ABA—Gbogbo awọn oṣiṣẹ ile ibiti nwọn gbe ti nṣe ọṣẹ lọdọ awọn Oyinbo Greek kan ti nwọn npe ile iṣẹ wọn ni International Equitable Associated Industry ni Aba ni nwọn binu da iṣẹ wọn silẹ nitoripe Oyinbo ọga onisẹ wọn ko fi owo kun owo oṣu wọn.

Irohin ti a gbọ nipa fa-raku awọn oṣiṣẹ na pẹlu Oyinbo ọga ile iṣẹ wọn ti nwọn npe ni P. D. Nicholas, ni pe lati bi ọjọ mẹta ni nwọn ti wa iẹnu rogbodiyan fi owo kun owo ngko fi owo kun owo na; ọrọ na deni, o deji, awọn oṣiṣẹ yi bẹrẹ binu lọ si ibi iṣẹ ti nwọn ba de ibẹ, nwọn a joko, nwọn ko ni fọwọ kan iṣẹ kan ṣe rara.

Nwọn ṣe bayi fun bi ọsẹ meji ki aiperi to wọ ọrọ wọn ni ọsan ijẹta. Oyinbo Nicholas onisẹ paapa wa fi aake kọri, o ni ki Ijọba ko fun on ni awọn ọlọpa nitoripe on fẹ ti ile iṣẹ na pa patapata, ki on silta a, ki on palẹmọ lati ma lọ si ilu on.

Tanu tanu ni Oyinbo na fi nṣe alaye fun awọn onise Ijoba ti o wa lati ba wọn da sii. O ni o le ni ọkẹ marun pọnun (£100, 000) ti on na ki on to le gbe ile iṣẹ ọṣẹ ṣiṣe na kalẹ, ere kọbọ on ko ti jẹ lori rẹ, o si to ọdun mejidinladọta ti on ti nṣe wahala lori iṣẹ na.

AKIYESI: A ri waya gba loru ana lati Aba wipe awọn oṣiṣẹ na ti lọ ba awọn onisẹ Ijọba wipe ki nwọn ba awọn ari ọrọ na, ki nwọn bẹ Oyinbo na ki o maṣe ti ile iṣẹ na, awọn yio pada sẹnu iṣẹ awọn lọsẹ ti mbọ.

### Sangba Fo Lona Ilugun:

## Igi Nla Yapa Awon Ero Inu Moto

ILUGUN (LETI IBADAN)—Sangba fọ loju ọna mọto Abẹokuta si Ibadan leti abule kan ti nwọn npe ni Adewusi nigbati igi nla kan ya lojiji lati inu igbo ti o si la mọto-akero kan, ti o nko awọn ti nwọn ti lọ ṣe ọdun Ileya ni Abẹokuta, wẹwẹ, ti o si pa'nia bi ẹni medogun ninu awọn ero ti oni mọto na nko lọ si Ibadan.

( Wo yoku loju ewe kejọ )

### Awon Enia - Dudu Jagun M'olu L'Amerika

BIRMINGHAM Ala.—Gba were ngko gba were, ọjọ kan ni a ko ọ awọn enia-dudu ti nwọn wa larin awọn alawọ funfun ilu Amẹrika, ti wọn ti bẹrẹ rogbodiyan iwa inunibini ti nwọn nhu si wọn dopin ni oru ana nigbati awọn alabẹ ṣekele ilu na pe ọtun ati osi jọ lati yanju ọrọ na fun wọn.

(Wo yoku loju ewe kejọ )

## Okunrin Ibo Kan Je Oku Ewure O Ku Taya Taya

ABAKALIKI—Ariwo ta ni ijẹta ni abule Idomi ni Obubra leti Abakaliki nigbati irohin kan awọn ara abule na pe ọkunrin agbẹ kan ti orukọ rẹ njẹ Ofeni Udi ti o ngbe arin wọn jẹ onjẹ ọsan tan, o si ku bamu pẹlu aya rẹ ti o njẹ Adue.

Irohin ti a gbọ nipa iku ojiji ti tọkọ taya na ku ni pe ni ọsan ijẹta nigbati Ọgbẹni Ofeni yi npada bọ lati inu oko rẹ, ni o ri oku ewurẹ kan ti nwọn ju si ẹ a-ọna, o sọ apẹrẹ ori rẹ kalẹ, o si sọ oku ewurẹ na si i.

Gbara ti o ti de abule ni o ti ni ki iyawo on fọ ikoko isasun, on na si bẹrẹsi kun ẹran na. Lẹhinti o kun un tan, o ge eyiti iyawo rẹ yio se fun un, o si ko iyoku si oju ina, o nyan wọn.

( Wo yoku loju ewe kẹjọ )

### Ijoba Ilu Amerika Fe ya Ibadan Lowo

Washington, D.C.,—Awọn alakoso Ijọba ilu Amẹrika ti ṣe ikede wipe awọn yio ya Ijọba Iwọ Orun ni owo gọbọyi kan ki nwọn le ri nkan lo fun ẹrọ-afami ilu Ibadan ti ko to lo fun gbogbo awọn ara ilu na nisiyi.

A gbọ wipe igba ọkẹ-o-le mẹdogun pọnun (£4.3 million) owo ti awọn Ijọba ilu Amẹrika na fẹ ya Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na, ogoji ọdun ni nwọn yio to san owo na. Lati ọdọ Ijọba Apapọṣe l'Eko ni owo na yio ti gba tẹ wọn lọwọ.

# Awon Alanu Oyinbo Ran Ilu Afrika Lowo Fun Onje

LONDON—Awọn alanu enia pọ pupọ kakiri ni ilu Oyinbo ti o fi jẹ wipe awọn ko kọ iyekiye owo lati na fun akọya tabi nkan ti o le mu anfani wa fun ẹnikẹni ni orilẹ-ede korilẹde ti onitọhun ti wa.

Laipẹyi ni gbogbo awọn orilẹede agbaiye ṣe ipade ti nwọn si ṣe ipinnu nla kan wipe awọn yio gbogun ti ebi ti o mba gbogbo araiye ja.

Eleyi mu ki olukuluku awọn Oyinbo da owo gọbọyi lati fi ra nkan iroko fun awọn agbẹ ni ilẹ awọn enia-dudu. Awọn miran ran awọn enia wọn ti mọ iṣẹ agbẹ ṣe daradara lọ si ilu Africa nititi ebi npa wọn, ti nkan ọgbin wọn ko hu daradara to.

Ọkan ninu iranlọwọ nla ti nwọn ṣe fun ara ilu Afrika na ni ẹrọ-iroko nla kan ti o wa ninu ọkan nimu aworan yiti awọn ọmọ ilegiga ni ilu Crawles ni England na'wo lati ra fun itọrẹ fun awọn agbẹ ara ilu kan ni isalẹ Afrika lati ma fi kọ awọn enia wọn ni iṣẹ oko-riro.

Aworan keji ni ti awọn oṣiṣẹ Ijọba meta lati ilu awọn Hausa ti awọn alanu ilu Oyinbo na ni ki nwọn wa si ilu awọn lati wa ko bi awọn ti nṣe Ijọba ilẹ wa.

Lẹhin eyin, nwọn tun ni ki nwọn rin gbogbo ilu awọn kakiri ki nwọn to pada si Nigeria.



## Tubman Tun Di Olotu Ile Liberia

MONROVIA—Awọn ara ilu Liberia ti tun yan Ọlọla William Tubman ni balẹ (Olotu) eto Ijọba wọn ninu idibo ti nwọn di ninu ọsẹ yi; eleyi ni yio di ẹkarun ti nwọn yio fi idibo yan sinu ipo bẹ, o si ni lati ṣe ọdun mẹrin gbako ninu ipo na, ki nwọn to tun yan ẹlomiran si ipo na.

A gbọ irohin lati Moronvia, tiṣe olu ilu Liberia, pe awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ti orukọ ẹgbẹ wọn njẹ Ture Whig Party ti bẹrẹ ba olori wọn yọ ayọ wọn si njo ijo kakiri arin ilu fun bibori ti awọn bori nibi idibo na.

Gbogbo awọn akọwe ile iṣẹ Ijọba paapa ni nwọn tun ṣe aṣeyẹ ti wọn na pẹlu ni ijẹta ọdẹ yi.

## E Ka Irohin Ayiluka Ti O Kun Fun Oro Ologbon Ati Oye Losose

NI ADE — ỌYỌ:

## Awon Osise Gba Iwe Idaduro

IBADAN — O ju adọta enia lọ ninu awọn oṣiṣẹ ti nwọn nṣiṣẹ ni ile awọn alaisan Ade-Ọyọ ti awọn ọga wọn ha ni iwe pe Ijọba da wọn duro kuro ni ẹnu iṣẹ wọn ni ipari oṣu ti a bọ si yi.

A gbọ wipe awọn oṣiṣẹ na ti kọ iwe-ẹbẹ ranṣẹ si Ọgbẹni J. E. Otobọ tiṣe minisita alamojuto eto ilera Ipinlẹ Iwọ Orun, wipe ki o gba awọn lọwọ ebi.



**Awon Iwe Asiko :**

## Fifi Owo Pamo Si Banki (3)

Ninu Iwe Alufa ATILADE

(O bẹrẹ lati ọsẹ to kọja)

### Iwe Eri

Nigbakugba ti o ba fẹ fi kun owo yi, iwọ yio mu iwe Banki pokiti ti a fun ọ yi wa iwọ yio si owo na le e, akọwe yio si kọ iye owo na sinu iwe rẹ ati sinu iwe nla ti Banki ni oju iwe ti a ti kọ orukọ rẹ si.

Ni ọjọ ti o ba fẹ gba ninu owo rẹ, iwọ yio mu iwe pokiti yi lọ si Banki iwọ yio si gba iwe pepe kan lọwọ Akọwe Banki.

### Lati Owo AKOWE

Gẹgẹbi aye ti a ti fi silẹ ninu iwe ibere owo gbigba pada yi iwọ yio kọ namba iwe Bank rẹ, iwe ti ofẹ gba, ọjọ oṣu ati orukọ rẹ ni ọna ti o ma fi nkọ ọ nigbagbogbo.

### Akowe Banki

Akọwe yio gba iwe yi ni ọwọ rẹ, yio si kọ iye ti o fẹ gba sabẹ iye ti o fi pamọ sibẹ, yio yọ o kuro ninu rẹ, yio si kọ iye ti o ku si isalẹ. Yio kọ orukọ ara rẹ si i, yio si fi ontẹ Banki tẹ ẹ. Yio kọ sinu iwe nla ribiti orukọ rẹ gbe wa iye ti o ti gba ati iye ti o ku ni ilẹ, yio si fun ọ ni owo ti o fẹ pẹlu iwe Banki rẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# Olopa Amerika Gbo gun Ti Enia Dudu

BIRMINGHAM, ALA. — Lati nkan bi ọsẹ kan ni awọn ọlọpa awọn Oyinbo alawọ funfun ti o wa ni ilu yi ti gbe ogun ti awọn enia-dudu ti o ngbe ilu yi nitori ipanpa ti awọn enia-dudu na so wipe ki nwọn ye se inunibini si awọn.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lati Amerika, inunibini ti awọn alawọ funfun ilu na nṣe si awọn enia dudu ibẹ lo mu ki nwọn dide tọmọ tọmọ lati fi aake kọri wipe awọn ni lati ma wọde kiri arin ilu wipe ki nwọn ye fi iya jẹ awọn nitori awọ ara awọn.

### Iwe Bibeli

Ni ọjọ Jimọ ti o koja yi ọrọ a faake kọri, a nwọde kiri na de gongo, olukulu awọn enia alawọdudu mu aṣọ leka, ọpọlọpọ wọn si gbe iwe BIBELI wọn lọwọ, nwọn nkọ orin, awọn miran nkigbe wipe ẸGBA WA KURO LỌWỌ AWỌN A-BINU ẸNI, WAHALA YI pọ ju o!

Ninu nwọn nṣe eyi lọwọ ni ọkunrin Oyinbo alawọ-funfun ara Amerika kan dide, ni o gbe moto-ayọkẹlẹ rẹ jade ti o nwa sare lọ si ibiti awọn enia na gbe nwọde gba, o fẹ fi moto rẹ na tẹ wọn pa.

### Aja Ode

Nigbati awọn enia dudu na de opopo kanawọn ọlọpa bẹrẹsi da omi le wọn lori,nwọn ni ki nwọn pada si ile wọn. Nwọn kọ, nwọn ko pada, awọn ọlọpa ilu na wa bẹrẹsi na wọn ni kunmọ.

Inakuna ni kunmọ ti nwọn ko bo wọn na, ati ọmọde ati agba, ko si ẹniti nwọn ko na ni anabole. Nigbati awọn enia na kọ lati pada sile wọn, aja ọdẹ ni nwọn dẹ si wọn, ti awọn aja na bẹrẹsi fa wọn laṣọ ya.

Oju ẹgba a enia lọmọde lagba ti awọn ọlọpa na ti ti mọle nisisiyi.


Comfortable and safe



A roomy 5–6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety, these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS: (EB): IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT. ABA.

SUB-DISTRIBUTORS:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

# ELETI—OFE

A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL XIV. No 868 SATURDAY MAY 11 MAY 17 1963


ỌRỌ OLOTU:

## Owo Riba Ko Dara..

Boya ẹnyin okawe wa ko ṣe akiyesi ogun a-da-ja ti awọn amuni-mada ọlọpa'nn kan gbe ti awọn oni-madaru Ọlọpa ode ti nwọn nfi RIBA JIJẸ ṣe avọ. Ninu ọsẹ ti o kọja ni Oyinbo ọga awọn Ọlọpanu l'Eko sọ ọrọ bonkẹlẹ kan fun awọn oniwe irohin wipe on fẹ ran awọn ọmọ iṣẹ on jade si igboro ilu Nigeria lati gbogun ti awọn ọlọpa ati akọwe ti njẹ riba lojojumọ.

A mọ wipe inu ẹnyin ara ilu yio dun pupọ lati gbọ irohin yi bi inu awa oniwe irohin Eleti—Ọfẹ pa-apa ti dun si ọrọ ikede ọga awọn Ọlọpa'nu na, ṣugbọn nkankan ni a fẹ ki ẹ mọ–iyẹn ni wipe 'ẹnikan kı jẹ awa de'

A bẹ ẹnyin ara ilu ni ọpọlọpọ ẹbẹ ki ẹ jọwọ lati r a n awọn a-muni-mada ọlọpa'nu yi lọwọ lati gbogun ti awọn akọwe ati ọlọpa ti ngba owo-ẹhin yi nitoriye iwa ọbaiyejẹ ni nwọn nhu.

### Ejo Elebi

Tani ko mọ wipe iṣẹ riba jijẹ yi ni awọn, ọlọpa yi fi nko ọrọ jọ. Nkan ti o bẹrẹ lati Eko de Nguru, lati Kaduna de Port–Harcourt mọ abule olorule kan, ko si ibiti awọn Ọlọpa wa ko le gba riba wọn. Bi nwọn ti ngba lọwọ ọmọde ni nwọn ngba l ọ w ọ agbalagba.

Bi enia ba gbe ẹsun ẹjọ lọ ba wọn nibi iṣẹ wọn ti Oluwarẹ ko ba le fi owo riba bọ wọn lọwọ, bi ẹjọ oluwarẹ ti wu ki o jẹ are to, ẹbi ni nwọn yio da fun oluwarẹ. Bi awọn ẹbi tabi ọrẹ oluwarẹ ko ba tete lọ wa owo ni ọnakọna, ki nwọn tẹ ẹ bọ awọn ọlọpa ti o ba wa nidi ọrọ ẹjọ na lọwọ, ọgba ẹwọn ni ẹlẹjọ na nlọ.

### Fun Alare

Ki a ma ti tori owo riba gbigba yi gbe ẹjọ ẹlẹbi fun alarẹ wọ awọn Ọlọpa wa lewu tobẹgẹ ti nwọn ko fi ka ẹmi enia si. Gbogbo ẹsẹ ti awọn oni-mọto akero ba ṣe lori ero ti nwọn ba ko ni awọn ọlọpa yi yi foju fo da. Eleyi ni o jẹ ki iku mọto pọ loju ọna-mọto ka'iri ilẹ wa lode oni.

Ki a wa pada sọdọ awọn ọga ile iṣẹ awọn bi akọwe - agba ti nwọn ni anfani lati gba enia si ibi iṣẹ; bi nwọn ko ba ri owo pọnla l a t i ọwọ ẹ, awọn ko ni gba ẹ sinu iṣẹ na bi o ti wu ki o mọ iwe to.

Bi o ba ni owo-riba lọwọ ko si ẹṣẹ kẹṣẹ ti o le ṣe ni ode aiye isisiyi ti o ko ni ṣe ẹ gbe. O bẹrẹ lori awọn ti ko ni iwe-ẹri lọwọ fun gbogbo nkan ti nwọn ni lati ni iwe-ẹri fun owo ẹhin ni nwọn fi yanju ẹ.

Ki a to pari ọrọ Olotu wa ti ọsẹ yi, o yẹ ki a tẹ mọ yin leti nkan ti ọga awọn ọlọpa'nu fẹ ki ẹ ma ṣe fun awọn ti ẹ ba ti ri, tabi ẹ gburo irohin iru awọn enia ti o ngba owo–riba bayi, ki ẹ jọwọ, ki ẹ jẹki awọn gbọ, awọn mọ bi awọn yio ṣe gbogun ti wọn lọtun losi. Ọrọ re o!

# Iwe Si Olotu

## Mo Gba Fun Ogbeni Onatade

Mo gba fun Ọgbẹni Ọnatade lori itan bi ERE SAKARA ṢE Bẹrẹ lọdọ awọn Imale Yoruba ni isalẹ odo ni ibi bayi ti o kọ sinu iwe irohin Eleti–Ọfẹ laipẹyi. Gbogbo wa ti a ka itan na ni a gbadun rẹ,

Gbara ti itan Ọgbẹni wa na jade tan ninu iwe Eleti—Ọfẹ na ni a gbọ ti awọn onişẹ redio, ẹrọ-asọ-rọ-ma-gbesi, bẹrẹsi tu pẹ-rẹpẹrẹ jade lori nkan ti Ọgbẹni Ọnatade na sọ nipa Ologbe Abibu Oluwa, onisakara Eko, ti o jalaisi ni aipẹ yi.

Ninu ere redio na, nwọn kọ orin diẹ ninu orin atijọ ti Ologbe Abibu kọ nigbati o kọ bẹrẹ ere sakara ṣe.

O ya wa lẹnu pupọ, nitọripe a ko gbọ ki nwọn kọ ọkan ninu orin Abibu na ninu redio ri. A ngbadun itan atijọ ti ẹ n t ẹ sinu iwe irohin yin.

Oko Baba, Ebute-Mẹtta

Emi ni,
Tijani Alabi

## Ede Yoruba Dun Ka..

Mo fi ara mọ ọrọ Ọgbẹni J. Ọladele ti o jade ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ laipẹyi lori ọrọ awọn IWE ASIKO ti Alufa ATILADE kọ fun awọn ọmọ ilewe ilẹ Yoruba.

O jẹ iyanu fun mi, ti mo ba pade ọmọ Yoruba ti o ti lọ kọ ẹkọ nilu Oyinbo, ti o ba sọ wipe on ko le ka Yoruba rara; oju a ma ti mi fun wọn.

Tani le sọ wipe ọrọ Aṣaro ti o wipe: "Ma kẹja aye ẹ, Bo ti wu ko ni po to" ninu IWE IKILỌ FUN AWỌN ỌDỌ ti Alufa Atilade na kọ ko kọ ni lọgbọn to nipa iwa hihu lode aiye?

Alufa Atilade, a gbadun yin, a si tun nfẹ itan abalaiye si.

Emi ni,
Jakọbu Ladun

Mushin


YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

# Odun Ileya

Ọdun Ileya ti ọdun yi dun pupọ, a fi ọjọ ti awọn kan kirun l'Eko ti ko ba ara won mu. Ilu meji pataki ni emi Ayiluka ṣe ọdun Ileya ti ọtẹ yi; mo ba wọn ṣe e lọjọ Jimọ ("Baba Rana, bi ede awọn Hausa) l'Eko, mo tun ba wọn ṣe ọdun na ni Abẹokuta ilu Ẹgba.

Ọdun Ileya kinni ti a o ṣe lẹhin iku Ọba Alake Ademọla Keji niyi ni Abẹokuta, ọdun na dun jọjọ. Gbogbo awọn ara oko ni nwọn wa sile tọmọ tọmọ; emi alara paapa je ifun eran agbo titi mo fẹrẹ ṣunnu. Bi awọn elepo pupa ti nta ni awọn oniyọ npa owo lọtun losi, ko si ẹniti ko ri iṣẹ owo ṣe.

### Ijebu Nile

Gbogbo awọn onimoto bọlẹkaja ni nwọn bu owo si owo-ero ti nwọn nko lọgan. Bi awọn moto yi ti nko ero lọ si Abẹokuta, ni nwọn nko awọn ọmọ Ijẹbu-lọkunrin lobinrin lọ si Ijẹbu—Ode ati Shagamu, awọn ara Ikorodu ni kilo subu lu awọn gbogbo wọn tan l'Eko.

Gbogbo awọn ara Ikorodu ti nwọn nta aṣọ ati awọn ti nwọn nṣe iṣẹ bauba (onigbajamọ) gerigeri, pẹlu awọn ti nwọn nta akara ẹgusi ati awọn ti nwọn nta botinni pẹlu owu-iranṣọ ni opopo Oroyinyin l'Eko ni nwọn ti lọ si Ikorodu fun ijo ẹlẹgbẹ ti nwọn ma nṣe ni ilu na lọdọdun.

### Baba Nigbogbo

Ni aiye atijọ, ọdun Magbo ni o ma nmu awọn ọmọ Ikorodu kakiri wa silu ṣugbọn Ọdun Ileya ti gbayi lọdọ awọn baba ati iya Magbo. Ko si nkan ti o fa eleyi ju aṣọ ati golu ti nwọn fẹ fi han awọn ara ile wipe awọn ri ṣe lẹhin-odi lọ.

Mo gbọ wipe ni ọla ọjọ Ọsẹ yi ni gbogbo awọn ara Ikorodu ati awọn ara ilu ti nwọn nṣe ni Gbogbo ni agbegbe Ikorodu na mbọ wa si ojude Ọba wọn lati jo ijo ẹgbẹ lọ si ita Iyalode Ikorodu ati ni Ita Ẹlẹwa, Emi Ayiluka na mbọ wa ba yin jo.

### Alanu Kano

Awọn agbalagba ni kaiṣa ku ẹnikan mọ - wa ṣugbọn ẹniti yio ku mọ wa na ni a ki tete mọ. Mo gbọ irohin lati ilu Kano wipe awọn alanu ilu Kano kan ni awọn fẹ ko Afin Ọba fun Ọba Kano ti ana ti nwọn wa kuro nilu tọmọ tọmọ. Ọrọ yi kiṣe awada, mo mọ awọn Hausa ti nwọn ba fẹ ran enia lọwọ. Oju kan ni ada ni ni ti awọn Hausa, nwọn kiṣe jodi jẹṣọ.

Nwọn ni awọn yio kọ Afin-Ọba na ni agbayanu ni ilu Azara ti nwọn wa ọba na lọ. Mo gba fun awọn alanu Kano yi, mo si gbọ wipe Ọba ana paapa nfẹ lati da ẹgbẹ oṣelu tirẹ silẹ, bi ilu Kano ni awọn ọmọ ẹgbẹ na yio maṣe kanpeni ti nwọn ni, bi Azare ni, bi Katangora ni, bi Sokoto ni, bi Kaduna ni, bi larin awọn ti nwọn npe ni Aana ni paapa Jos ni, iyẹn ni ko ti ye mi to.

Ju gbogbo rẹ lọ, ori Ọba Kano ana, Ọlọla Muhamadu Sanusi ko buru rara. Mo gbọ wipe ogoji agbo ati ogunfe eran ni ọba na pa fun ọdun Ileya na. Barika de Salla!

### Awon Olopa

Gbogbo nkan lo ni opin: nwọn ni nwọn ti gbogun ti awọn ọlọpa ti nwọn ngba owo ẹhin lọwọ awọn oni-mọto ati awọn ti nwọn lẹjọ ni Kotu kakiri. Mo gbọ wipe awọn ẹgbẹ oni moto-tasi (Taxi Drivers' Union) ni o lọ fẹjọ awọn ọlọpa ti o ngba riba yi sun.

Nwọn ni gbogbo awọn ọlọpa yi ati iyawo wọn lo ni moto-tasi nita ti nwọn fi npa owo nwọn ni wahala awọn ọlọpa na su awọn. Mo gbọ wipe o ti le logun awọn ọlọpa ti ọwọ ọlọpanu ti tẹ nisiyi. Aṣeju awọn ọlọpa wa pọ nitoọ. Ẹnyin akọwe ti ngba owo-ẹhin, ẹ ṣora, awọn Ọlọpanu wa labe tabili (table) yin o.

# Eleti Ofe

## D'araba




**he's going to fall!**

But YOU won't, if you make your plans for the future NOW — Don't procrastinate, Start with a Life Insurance programme Now and safeguard not only your own future but that of your children also. Consult

**GREAT NIGERIA**
INSURANCE
COMPANY LIMITED
(INCORPORATED IN NIGERIA)

Head Office: 39/41 Martins St., Lagos, P.O.Box 2314 Tel. 25251

Branches: Abeokuta, Agege, Akure, Benin-City, Ibadan, Ijebu-Ode, Ilesha Oshogbo, Sapele & Warri.

## IWE ASIKO

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ni Banki, o le ko le ji owo rẹ lọ, o le gba owo rẹ nigbakugba ti o ba fẹ; bi iku ba si de, awọn enia rẹ yio mu iwe rẹ lọ si Banki lati gba owo rẹ.

Anfani miran ti o tun wa ninu fifi owo pamọ si Bank ni pe, owo yi a ma le si diẹdiẹ lọdọdun bi o ko ba tete gba owo na pada.

### Owo Yiya

Anfani miran ni pe awọn enia bi onisowo yio ma ri owo ya lati ṣe wọn ni ilu rẹ, orilẹ ede rẹ yio si ma dagba ninu iṣẹ ati owo ṣiṣe.

Bi iwọ papa ba fẹ ya owo lọwọ Banki fun iṣẹ, Banki yio ya ọ nitoripe o jẹ onibara wọn.

AKIYESI: A mu ẹda ẹkọ yi lati inu iwe Alufa E. A. Atilade ti nwọn npe ni AKỌKA YORUBA apa karun ti gbogbo ile iṣẹ awọn Atawe nta kakiri Nigeria lọwọ lọwọ nisisiyi. Ẹ o tun ri omiran ka ni agbara Ọlọrun ni ọsẹ ti mbọ.

## IDIBO AWON ARA TOGO FAKIKI

LOME-Idibo ti awọn ara ilu Togo di ni ọtẹ yi fakiki, ni ọjọ ọsẹ ti o kọja lọ yi ni nwọn dibo na, sun gbọn lati igbati o ti ku ọjọ mẹta ni nwọn ti ṣe ofin wipe awọn ko fẹ ki ajoji kan wọn ilu awọn. Nitorina gbogbo oju ọna ti mọto mba wọlu wọn ni nwọn lọ ti pa bamu-bamu.

Ni ilu ti nwọn npe ni Palime, ni ilu Oke Togo, ni a ti gbọ irohin kan wipe awọn soja Togo gẹ okun waya ti o kọja nibẹ lọ si ilu ajeji; nwọn ni awọn ko fẹ ki nwọn mọ nkan ti awọn nṣe nipa eto idibo ilu awọn na.

A gbọ wipe awọn sọja ti nwọn ko si gbogbo oju ọna bode wọn na ko fẹ ri ara ilu Nigeria rara, nṣe ni nwọn nle awọn ero ilu Nigeria ti nwọn ba fẹ gba ilu kọja bi ẹniti o nle aja. Awọn sọja na ni ẹniti ko ba gbọ ti awọn, ti o ba kọja ibiti awọn ni ki o duro si, ibọn ni awọn yio yin pa a.

Lẹhinti nwọn ti ditẹ, ti nwọn ti pa, Dokita Sylvanus Olympio tiṣe olotu ilu na ni nwọn ti nṣe eto lati dibo yan olotu ijọba tuntun miran nitoripe awọn kan ni awọn ko faramọ ijọba pajawiri ti nwọn fi Ọgbẹni Nikolas Grunitzky ṣe alakoso rẹ.

A gbọ wipe awọn ẹgbẹ oṣelu Ọgbẹni Grunitzky ni nwọn fẹ mulẹ lori idibo na.

## Adoula Olotu Ilu Congo W'olu

EKO — Ọgbẹni Cyrille Adoula, Olotu ilu Congo, gba iyi, o gba ẹyẹ lọdọ awọn ara ilu Nigeria nigbati ọkọ ofurufu ti o wọ lati ilu rẹ gunlẹ si Ikẹja lọjọ Aiku (Sunday) ti o kọja yi. Awọn enia mẹtadinlọgbọn ni awọn ara ilu rẹ pẹlu iyawo rẹ ti o mu lọwọ.

Gbara ti o ti gunlẹ ni Olotu ilẹ yi, Ọlọla Abubakare Tafawa Balewa, ti sunmọ ọ, ti o si ki i ku abọ, o si gba a lọwọ. Lẹhin eyi awọn sọja ti nwọn to lọwọ lọwọ ṣe ẹyẹ fun un, on na si bọ si arin wọn lati yẹ wọn wo. Agba ibọn mọkandilogun ni nwọn yin fun un.

Ọgbẹni Adoula na ti lọ si Kaduna, Ẹnugu ati Ibadan. Onirohin wa ni on gbọ wipe ki ọrọ ajọrọ wọn le ṣe ikan ninu ipade irẹpọ ti nwọn fẹ ṣe ni ilu Addis-Ababa ni nwọn ṣe pe e wa si ilu Nigeria.

Ki Ọgbẹni Adoula na to pada si ilu rẹ ni ijẹrin, on pẹlu Ọlọla Tafawa Balewa na jọ ti ara wọn, nwọn si sọrọ laṣiri lori bi nkan ti nlọ si nipa awọn oṣelu Afrika.

JAPANESE BICYCLES



• STRONG
• SPEEDY
• SMART

TODAY JAPANESE BICYCLES COVER THE WHOLE WORLD

For import informations apply to:

JAPAN BICYCLE TRADE CENTER
P. O. Box 4117, BEIRUT LEBANON
CABLE EXBIKE BEIRUT

# Greater Beiram Celebration In London

## MUSLIMS WORSHIP IN LONDON MOSQUE

LONDON-Muslims throughout Britain on last Saturday celebrated Greater Beiram in traditional style.

At Britain's oldest mosque at Woking in Surrey, some 25 miles from London, some three thousand peope assembled; while at the Islamic Cultural Centre at Regent's Lodge, Central London, over five thousand gathered together, including most of the Muslim ambassadors in the metropolis.

The Moslem Women's Association organised a free luncheon which they distributed to the women present and th s was followed by a programme of religious songs and music.

Later a bazaar was held to raise funds towards the new London Mosque to be built in the Centre's grounds. Work is due to start in September and although completion will take about two years, it is hoped that the completion will be sufficiently advanced to enable next year's Id-El-Kabir to be held in the new building.

## Portable British Power Station

LONDON—A mobile electricity power station - it can supply the needs of a town of 10,000 people-was demonstrated by its British manufacturers yesterday.

The Bristol Siddeley unit is only 42 feet long and contain a 3 M.W. generator power.d by a 4,250 h.p. Proteus gas - turbin engine, originally developed as an aero engine.

The new unit can easily be transported by road, rail, sea or air.

It can be started from cold, synchronised with the grid and be on full power under one minute. It is also suitable for coping wite peak loads, emergencies and standby duties.

Bristol Siddeley pioneered the use of lightweight aero gas-turbines for industrial use. Already they h ve built fiv 3 M.W. and one 17 1/2 M.W. power stations in Britain. Orders from electricity authorities for similar equipment amount to m than £12-million.

The mobile version demonstrated yesterday is le ng England later this month on hire to the French Government to provide power at a construction site in Corsica.

## President of Cameroun Republic in Britain

LONDON-President Ahmadu Ahidjo of the Federal Cameroun Republic and Madame Ahidjo visited Oxford University, during their four-day official visit to Britain.

Before lunch they met a Camerounian student, Mr. Joseph Awunti, President of Oxford's African Society Mr. Awunti is a third year forestry student.

During his stay in London, President Ahidjo had talks with Prime Minister Mr. Macmillan and the Foreign Secretary, Lord Home. Later President and Madame Ahidjo lunched with the Queen at Buckinghan Palace.

**Read an Advertise In Eleti-Ofe weekly News Paper**

## British Rheumatism African Award For Nigerian

LONDON -- The first research award to be made in Africa by the Empire Rheumatism Council of Britain has been given to a Nigerian Doctor at Lagos University Teaching Hospital.

He is Dr C O Alele, Senior Registrar at the Hospital. The award, whih is for one year initially, is to help him in his research into the incidence and prevalence of rheumatic disorders in Nigeria.

"Since Dr Alele began his researches last October he has found six or seven different types of polyathritis among his patients" a spokesman for the Council told our correspondent.

This gives further substance to the evidence we already have that rheumatic disorders are not confined to cold climates and it is possible that Dr Alele's researches will be of importance not only for Nigeria but for other African countries."

The spokeman added that should Dr Alele's researches prove the need for similar investigation in other African countries, further awards would be made by the Council. The award to Dr. Alele brings the number of current projects the Council is supporting to a record total of forty-six.

# Princess Alexnadra And Mr Angus Ogilvy.



LONDON—A recent portrait of Princess Alexandra and her fiance, Mr. Augus Ogilvy, taken by photographer Cecil Beaton on the eve of their wedding which took place at Westminster Abbey, Lodon, recently.

Princess Alexandra is wearing a vivid pink blouse, pearl-and diamond earrings, and a diamond-and-ruby bracelet. Her engagement ring is of sapphire and diamonds.

## Okun Alasia Binu Ya Si'lu Kakiri

EKỌ—Okun ti gbogbo ẹnia mọ orukọ rẹ ni Okun Alasia l'Eko, ni a gbọ wipe o binu, o rn si arin ilu ti o wa ni agbegbe okun na ni alẹ ana.

A gbọ wipe ni ọsan ijẹta ni riru omi na kọ kan si awọn ti o ngbe agbegbe eti okun na, ere tabi awada ni nwọn kọ ṣe riru omi yi ṣugbọn nigbati o di ọganjọ ni nkanna tun bẹrẹsi le si.

Onirohin wa fi ye wa wipe bibinu omi okun na ko nṣe Okun Alasia nikan, gbogbo ẹru awọn apẹja ati ile ti nwọn kọ si Okun Apẹsẹ ni omi okun na baje patapata.

A gbọ wipe awọn Aganyin apẹja ti okun na pa ladanu aṣọ ati nkan dukia, ti nmura lati ṣe etutu ọdọdun ti nwọn ma nṣe fun orişa olokun ki o lẹ dawọn ibin rẹ duro.

## Awon Enia Dudu Jagun Molu Ni L'Amerika

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

Gẹgẹbi irohin ti a kọ gbọ nipa rogbodiyan wọn na ni ibẹrẹ ọsẹ yi, aja ọdẹ ati omi gbigbona mọ omi-tutu pẹlu gbongbo ọlọpa ni nwọn yọ si awọn enia-dudu yi nigbati nwọn bẹrẹsi wọde kiri, ti nwọn nlẹgun gbẹẹ wipe "Ẹ GBA WA KURỌ LỌWỌ AWỌN ABINU- ẸNI

Awọn Ọlọpa Oyinbo Amẹrika ti nwọn yan jade wipe ki nwọn lọ dẹrọ rogbodiyan na, inakuna ni nwọn nna awọn enia dudu na tọmọ tọmọ

A gbọ wipe Alufa Eniowọ Martin Luther King tiṣe olori awọn enia-dudu ti o nja fun ẹtọ wọn yi ti ṣe ikede ni oru ana wipe ọrọ na ti ndẹrọ, ọpọlọpọ nkan ẹtọ ti awọn nja fun ni nwọn ti ṣe ileri lati fun awọn.

Awọn ko fẹ ki awọn Oyinbo alnwọfuafun ilu Amẹrika ma le awọn ti ẹniti nle aja nile ijẹun (hotel), ile-ere (cinema), ile isin Ọlọrun (Church) Ṣọsi ati inu mọto bọọsi (bus) pẹlu ile iṣẹkiṣẹ.

Awọn enia-dudu ilu Amẹrika na ni Ọlọrun ti o da Rabi-Alaṣọ ni o da Rabi-Elewe; bi a ti bi ẹru ni a bi ọmọ, ibi ko ju ibi. Ki ọrọ na to ni iyanju o ju ẹgbẹtala (2,600) enia dudu ti awọn ọlọpa lọ ko da si itimọle lori ọrọ na.


HINDU SANKARA's
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries

Enclose 4/- money order by air Mail for Catalogues and Literature. HINDU SANKARA, 20 Montipelier Row, Blackheath,
EO/9
London, S.S.5, England.-


## Okunrin Ibo Kan Je Oku Ewure O Ku Taya Taya

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

Lẹhinti iyawo rẹ ti se ọbẹ tan ni awọn mejeji ba jọ joko, ni nwọn jọ jẹun, nwọn si jẹ onjẹ na ni a jẹ gbadun. Ko pẹ lẹhin eyi ni baba-agbẹ na ba sọ wipe inu nrun on, o si bẹrẹsi poholo, o mbi eebi, ko to to wakati kan o ti ṣubu lulẹ, o si ku bamu bamu; ki a to ri iṣẹju aaya, iyawo rẹ, ti o jẹ ninu ọbẹ oku ewurẹ na ti ku tẹle.

Awọn gbẹku gbẹku ile iṣẹ Ijọba ti wa ru oku wọn lọ si ile ilaku lati mọ nkan ti o pa wọn.

# Oloye S. L. Edu

### Ti Irin Ajo Meka De



EKO—Ninu awọn ero Mẹka ti nwọn gunlẹ si Ikẹja ni oru ana ni Oloye S. L. Edu, Magaji Ngeri Ẹpẹ ti o wọ ọkọ ofurufu ni iwọn ikan bi ijẹdogun ni Kano,

Gbgobo awọn ọrẹ rẹ ni o wa pade rẹ ni idikọ, ki o to lọ si Ẹpẹ ni ana lati lọ ri awọn ẹbi rẹ.

Oloye Edu pẹlu Lọya Fashinro ni nwọn jọ de lati Mẹku lana, awọn ni wọn kọ gunlẹ s'Eko ninu awọn ero Meka ọdun yi.

## Sangba Fo Lona Ilugun: Igi Nla Yapa Awon Ero Inu Moto

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Gbogbo mọto na ni iginla na run wẹwẹ ati ẹrọ ti o ngbe e rin, igi-nla na pa dẹrẹba ti o nwa a ni apafọn, ki a ma ṣẹṣẹ tun fẹnu kan awọn ero ti o joko tii niwaju mọ.

Ọmọ ilewe kan, Fatayi, ọmọ Alhaji Akorede ni Itoku, Abẹokuta wa ninu awọn ti nwọn ku nibi ijamba na ati Ọgbẹni kan ti nwọn npe ni Akinlabi, ti o nṣe iṣẹ ẹlẹtiriki, on na pẹlu iyawo rẹ ati awọn ọmọ wọn mejeji ni igi na ya pa.

Gbogbo awọn oku wọnyi ati awọn ti nwọn farapa ni nwọn ti ru wa si ile awọn alaisan ni Shekẹnu l'Abẹokuta ti awọn olokun nlọ gbe oku wọn ninu ile awọn lakulaku;

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Box 674
Phone 23370 Editor, (Ololu) Ola Onatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.